**OWE**

OKU eşinşin mu ororo ikunra olorun didun bajẹ ki o ma fi run oorun didun mọ. Bẹni were diẹ wuwo ju ọgbọn ati ọla lọ.

# Irohin Yoruba

No. 808 NOVEMBER 30 — DECEMBER 6, 1960 KOBO MEJI (2D)



Dara fun Ẹjẹ Ọmọde, Agba ati Aboyun

O wa fun tita kakiri Ile-ẹgbogi

# ADAJỌ ILỌRIN SỌ ỌLỌLA ỌLAWỌYIN S'ẸWỌN OṢU MẸFA

## *Ẹgbẹ Afẹnifẹre nja fun un*



ỌLỌLA J. S. ỌLAWỌYIN

**NI ọjọ Ọjọbọ ti işe ọjọ kẹtadinlogun oşu yi ni Adajọ Ijẹba Ibilẹ ni Ilọrin sọ Ọlọla J. S. Ọlawọyin, Akọwe Agba Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ẹka Ipinlẹ Ariwa, ati Aşoju ilu Ọffa ni ile Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ar wa na si ẹwọn oşu mẹfa fun ẹsun pe o mu awọn enia l'ọkan s'oke si Ijọba ati pe o nfẹ ba alafia ilu jẹ.**

Ẹgbẹ Afẹnifẹre si dide si ọro na, nwọn ti ke si Ajẹle-agba ni Ilọrin pe ki o gbe Ọlọla Ọlawọyin lọ si Kaduna bo tilẹ jẹ pe agbeyewo ẹjọ na wa niwaju Kotu nla ti Ipinlẹ Ariwa nipa kikọ ti Kotu Kekere ko lati gba iduro Ọlọla Ọlawọyin.

Ninu ikede ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre şe ni ọjọ Ẹti ti i şe ọjọ kẹdogbọn oşu yi, nwọn nfi han pe lati igbati adajọ ti da ẹjọ ẹwọn fun Ọlọla Ọlawọyin, ko ri ẹtọ gẹgẹbi ẹlẹwọn oşelu.

Gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Offa, ninu ipede nla kan ti nwọn şe laipẹ yi, fi ohun şọkan pe awọn gba pe Ẹgbẹ Afẹnifẹre jẹ ẹgbẹ oşelu pataki ti nwa rere ati anfani fun ilu, nwọn si tun f'owọ sọ'ya pẹlu pe awọn ni igbagbọ si itọnisọna Ọlọla J. S. Ọlawọyin, eniti Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Ilọrin sọ s'ẹwọn nitori ọrọ ilu.

Gongo sọ l'ọjọ ti awọn dajọ ẹwọn fun Ọlọla Ọlawọyin ni Ilọrin. Gbogbo ilu mititi l'ọjọ na.

Gbara ti Adajọ [illegible] na, Mallam Umoru [illegible] şe idajọ rẹ tan, [illegible] Ikẹrẹku ọlọpa ti fi Ọlọla [illegible] sinu mọtọ nla, [illegible] u lọ si ọgba [illegible] bi ibusọ meji si arin ilu. Bi mọtọ na si ti şi ni ogunlọgọ awọn enia ti o wa ni ita gbangba kotu na ba tẹlẹ e. Ọga awọn ọlọpa kan tẹle mọtọ na pẹlu.

**ỌJỌ KEJI**

Ni owurọ ọjọ keji ni nwọn ti wọ asọ ẹwọn fun Ọlọla Ọlawọyin ati awọn bi mẹwa ti nwọn ti ju sẹwọn pẹlu rẹ, nwọn si kọ wọn lọ si agbala Ọba Ilọrin lati lọ şa koriko. Nigbati nwọn yio fi şa koriko yi de ariwa ọja Ọba, awọn enia ti pe le wọn lori ti nwọn wa woran, nwọn pọ tobẹgẹgẹ ti awọn oşişẹ ati awọn akọwe ile-işẹ Ijọba

(Wo oju ewe kẹwa)

## Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun yio şi ile işẹ Ewekoro

ỌLỌLA Alaiyeluwa Adesoji Aderẹmi Ọni Ifẹ ti i şe Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun yio şi ile işẹ simẹnti ni Ewekoro (Ewekoro Cement Factory) ni ọjọ Abamẹta ti i şe ọjọ kẹta oşu ti o mbọ yi. Ile-işẹ na je ti apapọ awọn Western Nigeria Development Corporation", Portland Cement Company, Ltd. ati awọn Oyinbo Aladapọ "United Africa Company Ltd."



OBA ONI IFE
Gomina Iwọ-Orun.

## Ole kan ji iyawo gbe pẹlu ẹru onile

ONITSHA.

LAIPẸ yi ni nwọn mu okunrin onişowo kan ti oruko rẹ njẹ Moses Ijedeni eni odun medogbọn wa siwaju Adajọ Kotu Kekere ni Onitsha fun ẹsun pe o fọ ile, o si tun ji iyawo onile na ti oruko rẹ njẹ Blackie Okwuwi gbe pẹlu oogun.

Nwọn ni nigbati o wọ ile na, o ji ero iranşẹ (maşini) o tun ji igba ati okandinlogorin ponun (£279) owo Ogbeni Jacob Okwuwi.

### *Lakaye Ọrọ*

ỌLUKULUKU ohun ni akoko wa fun, ati igba fun işẹ gbogbo labẹ orun. Igba bibini ati igba iku. Iran kan nlọ, iran kan nbọ şugbọn aiye duro titi lai.

## Adegbenro jẹ oye Aşiwaju Musulumi Ẹgba

ABẸOKUTA.

IROHIN ko to afojuba ni ti aşeyẹ ti oye Aşiwaju Musulumi Ẹgba ti nwọn fi Alhaji D. S. Adegbenro, Minista Alabojuto Eto Ijọba Ibilẹ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun jẹ ni ọjọ Ẹti ti i şe ọjọ kẹdogbọn oşu yi ni Abẹokuta.

Ẹsẹ gbogbo awọn enia ja-nkan ja-nkan lọ pe sibi aşeyẹ na. Ni Mọşalaşi nla ni nwọn si şe eto oye na.

# Ẹgbẹ Ọmọ Ibilẹ Ọyọ ṣe ẹyẹ fun Adeniya



## Ẹsan ko ọmọ rẹ jade

OYAN.

## JAMES ADEOTI KỌṢẸ YANRI

ILOFFA, LEHA ILORIN.

## Adeogun

## Akigesi

OLOTU











# Shoyinka kọmọjade



MUSHIN.

# Ogbẹni Amusa Ladimeji gbe Modupẹ ni iyawo

KADE-GHANA.



# Awọn ọmọ ile Iwe Iloro ṣe ajọyọ Ominira Naijiria



ILORO, IJEBU.

## THE NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED

### CHRISTMAS SHILLING FUND DECEMBER 1960

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER

Ẹ ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun







Ẹnikẹni

ni o nra SIERA radio

SIERA NI AWỌN ẸRỌ-REDIO TI O DARAJULỌ NI NAIJIRIA

ni tirẹ LONI

JOHN HOLT

Ni o npin in ti o si ntun un ṣe yika gbogbo NAIJIRIA

Awọn Onişowo Ile-Itaja:- UTC DEPARTMENT STORES, LAGOS ATI AWỌN GBAJUMỌ ONIṢOWO NLANLA YIKA GBOGBO NAIJIRIA

## AKIYESI PATAKI

Eyi ni lati tun sọ fun nyin lẹkan si i pe, ẹnyin ti ẹ ti kọwe bere Iwe Irohin Yoruba ti 28:9:60 ati ti 5:10:60 ti ẹ ko i ti ri i gba, Ki ẹ mu suru fun wa diẹ si i, nitori a şi ngba wọn jọ silẹ nisisiyi lati pin wọn fun nyin.

Olotu




# Awolọwọ şe ikilọ nipa adehun lori aabo ogun



ESE awọn aşoju gbogbo onlwe irohin l'ope sibi ipade pataki kan ti Oloye Obafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aşiwaju Ẹgbẹ Alatako ninu Igbimọ Aşofin Apapọ Ijọba Naijiria pe l'Eko ni ọjọ 'Ru ti i şe ọjọ kẹtalelogun oşu yi nipa ọrọ adehun lori aabo ogun ti Apapọ Ijọba Naijiria şe pẹlu awọn Gẹẹsi.

Ninu ọrọ rẹ, Oloye Awolọwọ ni on ri i pe o yẹ o si to, ki awọn ara ilu Naijiria mọ nipa adehun na daradara. O şe alaye nipa ewu ati işina ti o wa ninu adehun na.

Aworan oke yi ni ti igbati Oloye Awolọwọ nba awọn onlwe irohin na sọrọ. Oloye Anthony Enahoro, ọkan ninu awọn oşelu Ẹgbẹ Afẹnifẹre lo joko si ọwọ osi.




Published by Allied newspapers Limited, Elephant House 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited. Fun owo "IROHIN YORUBA" odun kan—Eko sile mejo ati kobo mejo (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile mẹtala (13s.) Olotu S. A. Ademuyiwa, 2 Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin.